# AWỌN WOLII EKE TI IKẸYIN ỌJỌ́

## 2 Peteru 2: 1-22.

## ẸKỌ 455 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ mã ṣọ awọn ti nṣe ìyapa, ati awọn ti nmu ohun ikọsẹ̀ wá lodi si ẹkọ́ ti ẹnyin kọ́; ẹ si kuro ni isọ wọn" (Romu 16:17).**

### Ọrọ Mimọ́ Ọlọrun

Ọlọrun kò le purọ. Awọn ti wọn fẹ Ẹ mọ pe ootọ ni gbogbo Ọrọ ti o wà ninu Bibeli, pe gbogbo nnkan ti a kọ sibẹ ni a kọ gẹgẹ bi Ẹmi Mimọ Ọlọrun tikala Rẹ ti mí si awọn ti wọn kọ ọ silẹ. Awọn eniyan Ọlọrun tootọ gba awọn ẹkọ tabi iwaasu inu Bibeli gbọ́. Ki i iṣe pe wọn gbà wọ́n gbọ́ nikan, wọn n ṣe E, wọn si n gbé igbesi-ayé rẹ̀.

### Awọn Wolii Eke

Ṣugbọn ọ̀pọlọpọ eniyan ninu ayé ni wọn wi pe awọn gba Bibeli gbọ́, sibẹ wọn n kọ́ ni, wọn si n waasu nnkan ti o lodi si Ọrọ Ọlọrun. Nitori naa ni a ṣe kilọ fun wa ki a ma ṣe fetisi awọn wolii eke ki a má ba gba eke gbọ́ ki awa funra wa si má tan ẹkọkẹkọọ kalẹ.

Wolii eke kin-in-ni ti a kà ni pa rẹ̀ ninu Bibeli ni ejo ti o wá sọdọ Efa ninu Ọgba Edẹni. Ọlọrun ti sọ fun Adamu ati Efa pe bi wọn ba jẹ ninu igi ti o wa laaarin Ọgba Edeni, wọn yoo kú. Eyi yoo jẹ́ idajọ ti o banilẹru. O tobi ju pe ki ara wọn kú lọ. Wọn kú ikú ẹmi, wọn si já irẹpọ ti o wà laaarin awọn ati Ọlọrun. Ọlọrun ki yoo tun sọkalẹ lati bá wọn rin ati lati ba wọn sọrọ mọ́. Ejo naa wi pe. "Ẹnyin ki yio ku ikú kikú kan". Wọn gba ejo naa gbọ́ ju Ọlọrun lọ, a si lé wọn jade kuro ninu ọgba naa. Lati igba naa wa ni oniwaasu ati olukọ eke ti wà, ti wọn sọ pe Ọlọrun ni o rán wọn, ṣugbọn wọn kò sọ otitọ. Bi ẹnikẹni ba n waasu tabi bá n kọ́ ni ni ohunkohun ti o yatọ tabi ti o lodi si ohun ti o wà ninu Bibeli, eke ni oluwarẹ.

### Adámọ

Wolii eke le ti ri igbala lẹẹkan ri, o le ti maa waasu otitọ Ọrọ Ọlọrun ri. Ṣugbọn bi o bá wá ni ọna arekereke, o le jẹ pe pẹlu ẹtan lati yi ẹkọ otitọ tabi Ọrọ Bibeli pada, wolii eke ni. Jinna si oluwarẹ, ma ṣe ba a kẹgbẹ pọ. O n mu "adámọ ègbé" wá, bi iwọ si gba a, oun yoo mu ọ lọ si egbe ayeraye.

### Olojukokoro

Wolii eke a maa sẹ́ Oluwa ti o rà á, Oluwa ti o ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun un. O sẹ́ Oluwa nipa yiyi Ọrọ Rẹ̀ pada. O sẹ Ẹ nipa didá ẹ̀ṣẹ ti o si tun gba pe wolii Oluwa ni oun i ṣe. Awọn eniyan ayé n ri awọn wolii eke, wọn si n ro pe Ihinrere Jesu Kristi kun fun awọn agabagebe, wọn si n sọ ọrọ buburu nipa rẹ̀.

Awọn wolii eke wọnyii olojukokoro, awọn miiran n fẹ owó; awọn miiran n fẹ́ iyin eniyan; awọn miiran n fẹ ki awọn eniyan maa wò wọn gẹgẹ bi oniwaasu nla. Pẹlu ọrọ ipọnni, wọn "nṣowo", tabi wọn n rà wọn si n ta ẹmi awọn eniyan. Wọn n mu iparun ojiji wá sori ara wọn ati sori awọn ọmọ-ẹyin wọn --- idajọ Ọlọrun ti o n rọdẹdẹ sori wọn, ti o mura tán lati de ni igbakuugba.

### Idajọ ti o Daju

Lati fi hàn pe idajọ Ọlọrun daju lori gbogbo ẹlẹṣẹ, bi o tilẹ jẹ pe wọn ro pe wọn jẹ́ olododo, Aposteli Peteru sọ nipa awọn angeli ti o wà ni Ọrun nigba ti wọn dẹṣẹ, Ọlọrun sọ̀ wọn kalẹ si ọrun apaadi, O si fi wọn sinu ẹ̀wọn ninu okunkun, lati fi wọn pamọ de ọjọ idajọ.

Ni ayé atijọ, nigba ti Ọlọrun ri pe ẹ̀ṣẹ awọn eniyan di pupọ, ati pe iro inu wọn kiki ibi ni lojoojumọ, O rán Ikun Omi sori ayé awọn alaiwa-bi-Ọlọrun.

Nigba ti awọn eniyan Sodomu ati Gomorra buru to bẹẹ gẹ́ ti Ọlọrun ko ri olododo mẹwaa ninu wọn, Ó rán iná lati Ọrun, a si sun wọ́n di eeru.

Bi iwọ ti n ka awọn ọrọ wọnyii, iwọ yoo ri pe Ọlọrun dá Noa ati Loti si nitori wọn jẹ olododo. Ọlọrun ti ṣeleri lati yọ awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun, ṣugbọn idajọ Rẹ̀ yoo wá sori ẹlẹṣẹ kọọkan ti ko ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ki o si beere fun aanu, bi o tilẹ jẹ pe o le ṣe bi ẹni pe oun jẹ oniwaasu Ihinrere. Awọn ti wọn rọ mọ Bibeli gẹgẹ bi amọna wọn, ti wọn si jolootọ si awọn ẹkọ ti a kọ sibẹ, ni Ọlọrun yoo dá silẹ. Yoo gbà wọ́n silẹ agbara awọn wolii eke, yoo si gbà wọn kuro ninu idajọ nla ti n bọ̀ wá sori awọn alaiwa-bi- Ọlọrun.

**Ẹkọ Otitọ**

Bibeli ni Iwe wa. Bi a ti n kà á lojoojumọ, ti a si n gbadura pe ki Ọlọrun kọ ẹkọ rẹ̀ si ọkàn wa, a n kọ́ awọn ẹkọ rẹ̀, diẹ ninu wọn ni a kọ silẹ wọnyii:

**IRONUPIWADA** Olukuluku eniyan ni o ni lati ronupiwada tabi ki o kuro ninu ẹṣẹ rẹ̀ ki a ba le gba a la (Matteu 3:2).

**ATUNṢE** O ni lati ṣe atunṣe, o ni lati mú ohun ti o ti jí pada tabi ki o sanwo rẹ̀; o ni lati beere idariji fun eke ti o ti ṣe (Lefitiku 6: 1-5).

**IGBALA** Nigba ti o ba ri igbala, o ni igbala kuro ninu didá ẹ̀ṣẹ. O ri igbala nipa igbagbọ́ ninu Ẹjẹ Jesu (Romu 3:25), oun ko si dá ẹ̀ṣẹ mọ́ (1 Johannu 3:8, 9). Bi o ba dẹṣẹ lẹyin igba ti o ba ti ri igbala, ko ni igbala mọ́; o ti fasẹyin, o si wà ni ọna si ọrun apaadi, ayafi bi o ba ronupiwada.

**ISỌDIMIMỌ́** Ọlọrun wi pe, "Ẹ jẹ mimọ́, nitoriti emi jẹ mimọ́" (1 Peteru 1:16). Lẹyin ti ẹni kan ba ti ri igbala, a ni lati sọ ọ di mimọ́, nipa iṣẹ oore-ọfẹ ti o daju nipa Ẹjẹ Jesu. "Ẹ mã lepa alafia pẹlu enia gbogbo, ati iwa mimọ́, li aisi eyini kò si ẹniti yio ri Oluwa: Ẹ mã kiyesara ki ẹnikẹni ki o máṣe kùna ore-ọfẹ Ọlọrun; ki gbòngbo ikorò kan ki o má ba hù soke ki o si yọ nyin lẹnu, ọ̀pọlọpọ a si ti ipa rẹ̀ di aimọ́" (Heberu 12: 14, 15).

**IFI AGBARA ẸMI MIMỌ WỌ NI** Nigba ti ọgọfa ọmọ-ẹyin gba agbara Ẹmi Mimọ́ ati ina ni Ọjọ Pẹntekọsti Peteru wi pe, " Fun nyin ni ileri na, ati fun awọn ọmọ nyin, ati fun gbogbo awọn ti o jina rére, ani gbogbo awọn ti Oluwa Ọlọrun wa ó pè" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:39).

**IWOSAN NIPA AGBÁRA ỌLỌRUN** Ọlọrun ni oniṣegun ati oluwosan wa, a ni lati gbẹkẹle E nigba ti a ba ṣe aisàn. "Ẹnikẹni ṣe aisan ninu nyin bi? ki o pè awọn àgba ijọ, ki wọn si gbadura sori rẹ̀, ki wọn fi oróro kùn u li orukọ Oluwa: adura igbagbọ́ yio si gbà alaisan na là, Oluwa yio si gbé e dide" (Jakọbu 5:14,15).

**IPADABỌ JESU** Jesu tun n padabọ wá si ayé lẹẹkan si i. Lakọkọ yoo fara hàn ni awọsanma lati mú awọn wọnni kuro ninu ayé, awọn ti wọn fẹ Ẹ ti wọn si n ṣe ohun gbogbo ti wọn mọ̀ pe Bibeli palaṣẹ fun wọn lati ṣe (1 Tẹssalonika 4:17), nigba ti a o fi awọn alaiwa-bi-Ọlọrun silẹ ninu ayé yii lati jiya nigba Ipọnju Nla -- Idajọ Ọlọrun (Matteu 24:21). Nigba naa ni Jesu yoo pada wá sinu ayé pẹlu awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ lati ṣe akoso ati lati jọba fun ẹgbẹrun ọdún (Ifihan 20:4).

**ITẸ IDAJỌ NLA FUNFUN** Idajọ yii n duro de gbogbo awọn ti wọn kọ̀ lati wá igbala (Ifihan 20: 11,12). Nigba naa ni ayé yii yoo kọja lọ, ọrun titun ati aye titun yoo si wà (2 Peteru 3:13).

**ỌRUN RERE AILOPIN ATI ỌRUN-APAADI AILOPIN** Ọrun rere ailopin wa (Ifihan 22:14) ati ọrun-apaadi ailopin (Luku 16: 22-26; Ifihan 14:11) ti n jó pẹlu "iná ajõku" (Marku 9:43).

**KÒ SI IKỌSILẸ ATI ATUNGBE IYAWO** Isopọ igbeyawo de ni pọ̀ titi ayé. Ko gbọdọ si ikọsilẹ tabi atungbe iyawo niwọn igba ti alabagbe kin-in-ni ṣi wà laaye (Romu 7: 2, 3).

**ILANA BAPTISMU NIPA RIRI BỌMI** Iribọmi jẹ́ anfaani ati ojuṣe olukuluku ẹni ti o ba ri igbala. Lati ri ni bọ omi ni lati tẹ ni bọmi nipa lilọ sinu omi patapata, ki a si tún jade kuro ninu omi,

gẹgẹ bi Johannu ti ṣe iribọmi fun Jesu (Matteu 3:16). A si gbọdọ ri olukuluku bọ omi "li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ́"(Matteu 28:19), gẹgẹ bi Jesu ti paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀.

**OUNJẸ ALẸ OLUWA** Jesu tikara Rẹ ni o fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni ilana yii (Matteu 26:26-28), bi a si ti n jẹ akara ti a si n mu eso ajara, awọn ti i ṣe apẹẹrẹ ara Jesu ti a pa ati Ẹjẹ Rẹ̀ ti O ta silẹ, a n ṣe e ni iranti ikú Rẹ̀ lori igi agbelebu fun wa (1 Kọrinti 11:24).

**IWẸSẸ AWỌN ỌMỌ-ẸYIN** Jesu kọ́ ni ni ilana yii nipa apẹẹrẹ ti Oun tikara Rẹ̀ fi lelẹ wi pe, "Njẹ bi emi ti iṣẹ Oluwa ati olukọni nyin ba wẹ̀ ẹsẹ nyin, o tọ́ ki ẹnyin pẹlu si mã wẹ̀ ẹsẹ ara nyin. Nitori mo ti fi apẹ̃rẹ fun nyin, ki ẹnyin ki o le mã ṣe gẹgẹ bi mo ti ṣe si nyin" (Johannu 13:14, 15).

**Awọn Wolii Ti Wọn N Purọ**

Bi ẹnikẹni ba wá sọdọ rẹ ti o si wi pe Onigbagbọ́ ni oun, tabi pe oniwaasu Ihinrere paapaa ni oun, ti o si gbiyanju lati pa ọ́ laya dà lati gba pe ọ̀kan ninu awọn ẹkọ tabi ọrọ inu Bibeli ki i ṣe dandan, tabi pe a ni lati yi i pada, wolii eke ni oluwarẹ naa. Má ṣe fi eti si i, rìn jinna kuro lọdọ rẹ.

Awọn ti wọn bá fetisilẹ si ọrọ rẹ̀, ni yoo tàn jẹ, tabi ti yoo fà wọ́n sẹyin pẹlu ileri idasilẹ, nigba ti o ṣe pe oun paapaa wà ninu ide eṣu. O ti le ri igbala lẹẹkan ri; ṣugbọn bi o ba jẹ bẹẹ, o ti fà sẹyin, owe otitọ ni si ti ṣẹ si i lara, "Ajá tún pada si ẽbì ara rẹ̀; ati ẹlẹdẹ ti a ti wẹ̀ mọ́ sinu àfọ ninu ẹrẹ̀".

## AWỌN IBEERE

1. Bawo ni wọn ṣe bẹrẹ "adámọ" egbe wọn?
2. Ki ni adámọ?
3. Bawo ni awọn wolii eke ṣe n sẹ́ Oluwa?
4. Bawo ni a ṣe mọ̀ pe idajọ Ọlọrun yoo wá sori ẹlẹṣẹ kọọkan ati gbogbo ẹlẹṣẹ?
5. Irú awọn eniyan wo ni a n yọ kuro ninu idanwo?
6. Sọ orukọ wolii eke ti a darukọ ninu ẹkọ wa.
7. Inu irú ide wo ni awọn wolii eke wà?
8. Owe wo ni o fi igbẹyin ti o banilẹru ti awọn afasẹyin wà hàn?